# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VLO XIV NO 900 LAGOS SATURDAY DEC. 21 — DECEMBER 27 1963 KỌBỌ MEJI (2D)


**Eleyi Ara!**

# Iya Alawo Toku L'Eko Jidide Nilu Saro, O Fowo Ran Enia Sile

**Freetown** (Sierra-Leone)—Ọrọbẹ hin yọ ni adugbo kan ni ilu Saro (Sierra-Leone) ni Freetown nigbati awọn ara Eko ti nwọn ngbe ilu na gbọ wipe obinrin gbajumọ kan ti o de sọdọ wọn laipẹ yi ti jalaisi ni Eko ki o to wa be wọn wo nilu na.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ nipa ọrọ na, Obinrin ti o nta awo-tanganran kan ku leti Ita Balogun laipe yi, nwọn si sinku rẹ ni alarinrin gẹgẹbi nwọn ti nsinku gbajumọ l'Eko, ṣugbọn nigbati o di ijẹtẹ ni ọkunrin ara Eko kan ti Ologbe obinrin na de sọdọ rẹ ni Saro ba ọkọ omi de s'Eko o si lọ si ọdọ awọn ẹbi rẹ ti oku na ranṣẹ si.

Onirohin wa ni nigbati Ọgbẹni na de ibẹ o bẹrẹsi iṣẹ bi iyawo onitanganran na ṣe na ṣe de sọdọ on ni Saro, tio ni dokita ni o sọ wipe ki on wa gba alegun ni O e- Okun fun amodi kan ti o ti ṣe on. Ọgbẹni na ni iya alawo ayọrunbọ na ko apoti pọtimanto kan

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

OYE ỌDUN MẸRIN DI KAYEFI:

## Awon Ara Owu Faake Kori Lori Oye Ti Ijoba Fe Gba Lowo Adegbenro

AGỌ OWU ABẸOKUTA— Igba meji ko lu ara wọn pọ ni Agẹ Owu lati ijeta ti awọn awọn ara Owu ti gbọ irohin nla kan wipe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Ọrun ti fun Minisita alamojuto eto Oye, Ọgbẹni R.A. Akinyemi ni aṣẹ wipe ki o kọwe si Ọba Gbadela Keji Ọba Olowu wipe ki Ọba na gba Oye Balogun Owu ti awọn ọmọ owu fi Alhaji D.S. Adegbenro jẹ ni idunnu lọwọ rẹ.



ALHAJI D.S. ADEGBENRO

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


## LAGOS RACE CLUB

SUNDAY 22nd, THURSDAY 26th, SUNDAY 29th DECEMBER, 1963 WEDNESDAY 1ST AND SUNDAY 5TH JANUARY, 1964.

Racing Starts at 3.30 p.m. each day of the Meeting.

Declaration.

Declaration will be made at the Secretary's Office between the hours of 1.30 p.m. and 2 p.m on racing days

Admission Ticket/Programme 4/- per day including Entertainment Tax.

Children.

No Children under the of age of 14 years will be permitted to enter the Members Enclosure.

Sweepstake.

On each day's race Meeting a Sweepstake will be drawn on the number of Admission Tickets. 1st will be paid £2. 10/-, 2nd £1. 10/- and 3rd 10/-.

Silver Cups

ALSO Two Silver Cups will be presented to the best dressed Ladies in National Costume and Western Dress on the last day of this meeting.

Special Horses from the North entered for this Meeting including seven from the Emir of Zaria's Stable. Look forward to BIGGER DIVIDENDS.

# Adetunji Ajala Komojade Ni Ebute Metta

EBUTE MẸTTA— Laipe yi ni Ọgbẹni Joseph Adetunji Ajala ko ọmọ ti iyawo rẹ, Iyaafin Taiwo Ajala ṣẹṣẹ bi fun un jade ni ile ti nwọn ngbe ni namba meji ni opopo adugbo ti nwọn npe ni Thomas Street leti Mosalasi Olokodana ni Ebute Mẹtta.

Gbogbo ẹsẹ awọn Ijọ Ṣọsi Onitẹbọmi (Ijero Baptist) ni nwọn pe sibi isomọ loruko na ati awọn ọmọlẹbi Ajala ti Ijaiye ni Abẹokuta pẹlu awọn ọmọ Owu. Nwọn sọ ọmọbinrin na ni Ọmọlara Aṣabi.

Aṣeyẹ ọjọ ikomọ na ka mọmọ, Ọgbẹni Taninọwo (BABA GARDEN OF EDEN) ni nwọn fi ṣe alaga aṣeyẹ ikomojade jade na; awọn onilu kan ti wọn npe ni ADE ni nwọn wa ṣere nibi ikomọjade na.

Gbogbo awọn ti nwọn wa sibi aṣeyẹ ikomọjade na ni baba ọmọtuntun na fi nkan jijẹ ati mimu tẹ lọrun.

Awọn diẹ ti a le darukọ niyi ninu awọn ti nwọn wa sibi aṣeyẹ ikomọjade na awọn bi Ọgbẹni Onifade ati aya re, P Ade Okesanjọ, J Ọladoyinbo Ajala ati aya rẹ, A Arigbanla ati aya rẹ, S Suberu, Ọlalekan Ọnatade, Ọlajide Ajala, Ọlaniran Ajala Ajao ati aya rẹ, Okunlọla ati ọpọlọpọ awọn oṣiṣẹ ile ti nwọn ti nrọ ọti bia (Nigeria Brewries ni Iganmu leti Apapa.

Ọlọrun ko da ọmọ na fun awọn obi rẹ.

# Adajo Ni Ladipo Maja Kuro Nile Fun Baba Re

EKO — Nwọn pari ẹjọ ile Dokita Akinọla Maja ti o ni Ita Akanni l'Eko ti o titori rẹ gbe ọmọ rẹ Ọladipọ lọ si Kotu wipe ki o kuro nile na fun on nitoripe on fẹ lo o, ti nwọn ti tori rẹ gbe ara lọ si kotu nigba kan, ni ijẹta.

A gbọ wipe ọmọ na ti sọ fun lọya rẹ wipe ki o sọ fun adajọ ti nwọn nro ẹjọ na ni iwaju rẹ wipe on ti gba lati fi gbogbo ile na silẹ on si ti san oko-le-ni-irinwo pọnun owo ile ti on jẹ baba on na.

Baba rẹ, Dokita Maja ni adọrun le nirinwo pọnun (£490) ni gbogbo owo-ile ti ọmọ na jẹ on, baba na ni on yafi owo yoku fun ọmọ na.

# Ra ELETI-OFE

(... ni ose ti o mbo, OLOFINTOTO ...a awon omo Igbomina soro pataki,

# Iwe Si Olotu

## Awon Olopa Eko Tun De!

Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye ninu Eleti Ofẹ lati kesi awọn ara Eko ki nwon tete dide si ọrọ awọn Ọlọpa Ijọba Apapọ ṣe ti Eko ti nwọn ko jẹki awọn iyawo yin simi, ti nwọn nle kiri lọja nitoripe nwọn nkiri ọja lati pese onjẹ fun awọn ọmọ wọn.

Mo gbọ wipe ọrọ a nfi Ọlọpa leni kiri ọja yi ti kuro lọwọ awọn Kansilọ Eko patapata, eyiti o wu awọn Ọlọpa ni nwọn nṣe, boya ki nwọn le ri owo pa sapo Ijọba ni nwọn ṣe nṣe bayi ko ye wa si.

Ẹ jọwọ ẹnyin obinrin ara Eko, mo fi Olokun ati Ọlọsa bẹ yin, ẹ mura ki ẹ kigbe lọ ba Ọlọla Tafawa Balewa wipe ki Ọlọpa ye le yin kiri. Enia Ọlọrun ni Ọlọla Balewa yio gbọ ọrọ yin.

Emi ni,
Eko O. Adeniji

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE
KEROSINE
L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le rí rà nibikibi, ko si wọn, o mó daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, iná-titàn ati lati mā fi yáná Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

## Akoka Yoruba:

# Eto Igbeyawo Ni Ile Yoruba (1)

Lati ọwọ Alufa E. A. ATILADE

Olukuluku orilẹ ede ni o ni aṣa bi nwọn ti ngbeyawo ni ilu wọn. Aṣa adaiyeba bi awọn Yoruba ti nṣe eto igbeyawo ni ilẹ wa ni aiye atijọ ti Alufa (Rev) E.A Atilade, olukọwe kan ti gbogbo yin ti nma gbọ okiki awọn iwe ti o kọ fun lilo awọn akẹkọ nilẹ Yoruba, kọ iwe lori rẹ ni a bẹrẹsi tẹ jade fun ẹ n y i n ọkawe wa lati ọsẹ yi lọ. Itan igbeyawo na bẹrẹ pẹlu arofọ orin kan bayi:

" Iyawo dun gbe.
Ọmọ dun ko jade;
Ẹni o f'arugbo,
Ni' ahọn rẹ la 'ru,
Ẹni fẹ panṣaga,
Ni' ahọn rẹ b' agbo
Ẹni o fẹ ọgbọgbọ yawo,
Ni' ahọn rẹ la igan oyin."

Ni ilẹ Yoruba, awọn obi gba pe iṣẹ ti nwọn ni lati gbe iyawo fun ọmọ wọn ti o jẹ ọkunrin nitoriua nwọn ama fo'ju sode lati wa ọmọbinrin lati idile dada ti o le jẹ aya fun ọmọ wọn.

Bi nwọn ba gburo pe a bi ọmọbinrin kan ni idile dada nwọn yio tete lọ sibẹ, nwọn yio si wipe, 'Ẹ ṣe wa l'Ebu o, Awa ni a o fẹ ọmọ nyin o." Lẹhin eyi, bi ẹlomiran ba de ti o si tun wi nkan kanna, nwọn yio da a lohun pe "Ẹnikan ti ṣaju yin o."

Ni ọjọ kẹjọ ti a o ko ọmọ na jade, iya ọmọkunrin to fẹ fẹ ọmọ na fun yio mu kanyinkanyin ọṣẹ osun ati adi pẹlu ẹru igi kan ati ẹgbẹrun (3d) wa bi ẹbun fun ọmọ na. Ẹbun yi yio fi han awọn obi ọmọbinrin na wipe awọn obi ọmọkunrin ti o fẹ fẹ ọmọ wọn fuu ko fi ọrọ na ṣe are.

Awọn obi ọmọkunrin na yio yan ẹnikan ti o sunmọ obi ọmọbinrin na dada ni alarina, ẹniti yio ma ṣe aṣoju wọn niwaju awọn ọmọbinrin na. Lati igba yi ni awọn obi ọmọkunrin na yio ti mu awọn obi ọmọbinrin na gẹgebi olore wọn, nwọn yio si ma fi imore wọn han fun awọn ana wọn wọnyi nipa ikini ati iyẹnisi tọwọtọwọ. Bi o ba di akoko elubọ, nwọn a gbe ẹru elubọ kan wa laisi obi ati adiẹ ninu. Iṣu maruu ati ẹyọ elubọ mẹdogun ni ẹbun ti alarina lọdun.

Nigbati ọdun iṣu egbodo ba de, nwọn yio di ẹru iṣu kan (iṣu mẹsan) pẹlu adiẹ kan ati obi mẹsan lọ fun iya ọmọbinrin na fun itọju iyawo wọn ti o wa lọna.

Nigbati ọmọbinrin na ba di ọmọ ọdun bi marun awọn obi rẹ yio ranṣẹ si awọn obi ọkọ ọmọ wọn wipe ki nwọn wa da ifa aya wọn. Awọn obi ọmọkuarin na yio ra obukọ kan lati da ifa na.

Ni ọjọ ioafa yi, nwọn babalawo yio mu ki ọmọbinrin na kunlẹ niwaju ọpọn ifa, nwọn yio si bere lọwọ Ifa bi igbesi aiye rẹ yio ti ri bi o ba fẹ ọmọkunrn na. Bi Ifa ba fọ ire, nwọn yio pa obukọ na, awọn yio si ro ẹjẹ rẹ si ori ẹkọ tutu ti o wa ninu igba ti ọmọbinrin na gbe lọwọ. Lẹhin na ọnọ na yio gbe ẹkọ na lọ si Idi Eṣu li ode, yio si pada wa sinu ile, awọn babalawo yio si sure fun un.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

## Ija Ko D'ola, Ṣugbon ......

# Njoku Ni BensonKo Gbowe T'on Rara

Ọrọ emi OLOFINTOTO k... i po ... poju ni ọse yi ṣugbọn o yẹ ki njẹ ... ẹnyin ti ẹ nka iwe Eleti Ofe ni ọsọsẹ fi eti yin kọ awọn nkan diẹ ti mo fi eti kọ larin ilu yi ati lẹhin-odi ninu ọsẹ ti o kọja yi.

### Ise Eti Ebute

Bi mo ti gbọ ọrọ aawọ ti o wa larin awọn ọsẹ u wa nipa ọrọ awọn ogunlọgo lebira ti nwọn fẹ da silẹ nibi iṣẹ ọkọ eti ebute ti ọpọlọpọ ẹnyin ara Eko ma npe ni iṣẹ Biney ni Apapa, o dabi eni wipe ọrọ na b'Ige b'Adubi larin awọn ẹmọ ẹgbẹ oṣelu ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni ilẹ yi .

## Lati Owo Olofintoto

Bi o ba dabi ẹni wipe irọ ni mo pa, kini d u n Ọgbẹni Raymoud Njoku minisita alamojuto eto ọkọ ilẹ ati ti ofurufu ti o fi ṣi nkan ti osọko ọrọ lu Ọgbẹni TOS Benson, minisita alamojuto eto irohin Ijọba ti o fi sọ wipe: EMI NSỌ EDE OYINBO DARADA RA JU ỌGBẸNI T.O.S. BENSON LỌ ATI wipe on ṣe A G B A BENSON LẸNU I Ṣ Ẹ MINISITA ṣiṣe ati NINU ẸGBẸ OṢELU TI AWỌN JỌ WA?

### Ija Nla Niyi

Ọgbẹni Njoku un wa ṣe alaye lori ẹbolohun ọrọ ti o ngba Benson na wipe ẹkọ-ile ti nwọn fun olukuluku ninu ile wọn yatọ nitorina ni on ṣe dake, ti on ko fẹ ba Ọgbẹni Benson ṣe ẹrẹkẹ eebu ninu iwe irohin atiọdọ awọn oni redio.

Njoku ni ọrọ iṣẹ eti ebute ọkọ ti Benson nṣe lalakoko-fẹfẹ si ko to nkan ti enia le g b e p ọ n nitoripe ọrọ b'o n k e l ẹ ni awọn ni lati sọ ọrọ na larin ijoko awọn minisita nigbati awọn ba nṣe ajọ. O ni ọrọ iṣẹ ebute na ko tilẹ ye Ọgbẹni Benson daradara. o ni bi o ba yẹ e a mọ wipe awọn alagbaṣe iṣẹ ebute ilu Eko ni nwọn ṣ'o rire dinu iṣẹ na pudọju

### Egbon Njoku Nko?

Ẹnyin ọkawe mi, a agbọ gbog o alaye ati ẹnu ẹkẹeebu ti Ọgbẹni Njoku nṣe lori ọrọ Biney l'Ap pa yi, ṣugbọn ọrọ na dabi ẹniti o fi ẹtẹ silẹ, ti o npa lapalapa; ọrọ ẹkẹ eebu kọ ni a fẹ ki Raymond Njoku fi ọrọ iṣẹ awọn lebira ebute ṣe bikoṣe ọna ti yio gbe ọrọ na gba ti ko fi da awọn ẹgunlọgọ lebira Apapa duro lẹnu iṣẹ wọn lọjọ mẹwa leni.

### O Fe Gba Ise Bi?

Lati ọjọ ti rogbodiyan ọrọ iṣẹ ebute ti bẹ silẹ ni mo ti afi imu finlẹ kiri lati mọ nkan ti o fa idi rẹ. Ṣe o yẹ ki enia wa idi ohun gbogbo tonitoni.

Awọn Yoruba ni egungun ẹran ti a ba so si aja lọrun, aja ko gbọdọ san an rara. Mo gbọ wipe Minisita alamojuto eto ọkọ ilẹ ati ọkọ ofurufu, Ọgbẹni Raymond Njoku ni ẹgbọn kan ti orukọ rẹ njẹ Bernard Njoku ti

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

**Nile L'oko Lalejo Lonile A Ki Gbogbo yin Pe E ku Ipalemo Keresimesi**


**HINDU SANKARA'S**
**Religious Art Jewelleries**



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 4/- British Postal Order by airmail for catalogues and literature.*

HINDU SANKARA, 431 Archway Road, London, N.6, England

# ELETI-OFE

(ANJU WON KOSE WI LEIO)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAME
26, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFE" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL XIV. NO 900 SATURDAY Dec 21. - Dec 27, 1963,

## Oro Olotu:

# E Ku Ipale-mo Odun Kereismesi

Ki o to to ọjọ mẹta si a o ti bẹrẹsi ṣe ọdun KERESIMESI, nitorina ni awa Eleti-Ọfẹ ṣe fi ẹsin ọrọ wa ti ọsẹ yi ki ẹnyin ọkawe wa jakejado ilẹ Nigeria wipe ẹ ku ipalẹmọ ọdun Keresimesi na; ṣugbọn a fẹ bi ẹnyin ọkawe wa ni ibere kan, ibere na ni: kini itumọ ọdun KERESIMESI (Xmas) ti a mọ nṣe ni ọdọdun yi ?

Ọdun Keresimesi jẹ ỌDUN ALAFIA ati ỌDUN IFẸ. Kiṣe ọdun jagidijagan ti ọpọlọpọ awa enia nkaa si loni. Kiṣe ọdun ọlọti ti gbogbo wa ti fi ko igo bia ati keregbe ẹmu sile lọjọ oni. Ọdun lati fi ifẹ han fun awọn aladugbo wa ni, kiṣe lati fi aṣọ ati bata tuntun han wọn.

### Aiye Dukia

A gbọ wipe nigbati Jesu Kirisiti, ẹniti a fẹ ṣe iranti ọjọbi ti iya rẹ bi, wa ni aiye, ko fi ọrọ ẹnu rẹ ati nkan ini rẹ pa ẹnikan lẹkun rara. Ko fi igba kan ko dukia jọ. Ko si fi igba kan huwa alọnilọwọgba, ẹyiti o ti wọ gbogbo wa lẹwu ninu aiye nisisiyi, titi ti o fi jade laiye.

Jesu Kirisiti ko fi igba kan ko awọn ABỌBAKU ENIA SEHIN, ki o ma sọ wipe: "ALAGBARA DE Ẹ YAGO LỌNA fun un" kiri. Iwa ti o nhu ni gbogbo ilu ti o nwọ ni nwọn ṣe npe e ni ỌMỌ ỌBA ALAFIA, kiṣe lori ijangbọn ti o fa ati awọn to pa lẹkun.

### Aiye Alagbara

Ni ode oni, ọkan awọn alagbara paapa ko balẹ ojojumọ ni nwọn nrọ orukọ-ija sinu apẹtẹ ti nwọn tun nko awọn ARẸNIBAKU sẹhin boya a le ri ẹniti yio kọlu wọn tija tija. Ọjọ melo ni a o ṣe eleyi gba?

Awọn agbalagba ni iwa ọmọ ni mu ọmọ ṣe ogun oki'gbẹ. Bi ara wa ba mọ, ti a fẹ ẹnikeji wa gẹgẹbi ara wa, ti a ko pa ẹnikẹni lẹkun pẹlu iwa wa ojojumọ, ko si ọna ti inu awana ko fi ni ma dun ti nwọn yio si ... pe ... a ni ọmọ alafia.

Ni ẹkan si, a ki yin, ẹ ku ipalẹmọ ọdun. Ẹ ṣọ... aje ki a pade agbako iku mọto lọna.

# Iwe Si Olotu

## Enyin Igbomina, Iro Ni Titus Pa Bayi!

Olotu, ẹ jọwọ ẹ gba mi laye diẹ ninu iwe Eleti-Ọfẹ lati le ṣe ikilọ fun gbogbo awọn ọmọ Igbomina ati Ọffa ti mbẹ ni idalẹ ati nile nipa awọn kan ti nwọn tun nfẹ da rudurudu si arin wa pẹlu awọn ara Ilọrin lori ọrọ Ijọba ibilẹ fun ilu Igbomina, Offa, Ekiti ati Odo Ogun ti a ti nja fun.

O jẹ nkan ti o ya mi lẹnu pupọ lati ri irohin ipade kan ti ko wa saiye (ti a ko ṣe rara) ti Ọgbẹni Titus Adeoye ti o ni on ṣẹṣẹ jẹ oye Balogun sọ wipe awọn ọmọ Igbomina ṣe laipẹ yi.

O ni ninu ara sọ ipade na, o ni gbogbo awa ọmọ Igbomina ti a wa nibẹ ni a fi aake kọri wipe ti awọn ara Ilọrin ko ba fun wa ni Ijọba ibilẹ ti a nfẹ, gbogbo owo-ori ti a ba da ni ao ko lọ si Kaduna funra wa.

Mo fẹ ki Ọgbẹni Adeoye jọwọ ki o dar kọ alagba ti o ṣe alaga ipade ọjọ na fun wa; ekeji tani awọn enia pataki ọmọ ẹgbẹ Igbomina Parapọ ti nwọn wa sibi ipade na, ẹkẹta tani yan Titus Adeoye alara paapa ni akọwe ẹgbẹ; ẹkẹrin ninu ile wo ni nwọn ti ṣe ipade na.

Ẹ jọwọ ẹ ba wa ṣe ikilọ fun iru awọn enia bi Titus Adeoye bayi ki nwọn jọwọ ye ṣi awọn enia lọna pẹlu irohin ti ko ba ja gara bayi.

Mo dupẹ pupọ lọwọ yin fun aye ti ẹ gba mi, Olotu, iwaju ni ẹo ma lọ, ẹ ko ni pade agbako.

Emi ni,
Igbomina, S. Aroworọwọn
lẹba Ọffa.

---

## Eleyi Ko Ye Wa o!

Ẹ jọwọ Olotu, ẹnyin ni ẹwa l'Eko ti ẹ nri ihin, ti ẹ ri ọhun, ti ẹ nri ibi gbogbo, ẹ jọwọ ẹ la ọrọ awọn ọmọ ẹgbẹ kan ti nwọn ni Ẹgbẹ ọmọ Yoruba ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ ye wa nitori pe a ri awọn kan ti nwọn wa polowo ẹgbẹ na ni ọdọ awọn ijoye wa laipẹ yi.

Awa fẹ mọ bi ẹgbẹ ibilẹ ọmọ Yoruba ti a npe ni ọmọ Oduduwa ba ti fọ ni nitoripe ko ye ki a ma huwa a ri iyawo kọ iyale.

Gbogbo awa Yoruba ni a ko ni gbagbe iṣẹ rere awọn ọmọ ẹgbẹ Oduduwa lara wa, ti ẹgbẹ tuntun yi ko ye wa rara o.

Emi ni,
Iperu, Eman Shokọya
Ijẹbu Rẹmọ

**Pa Eleti-Ofe tire ni ose ti o mbo Olofintoto yio ba awon omo Igbomina soro pataki.**

## A ko fe Ijoba Alapa kan

Laipẹ yi ni a gbọ irohin ọrọ kan ti Oloye Dennis Osadebay Olotu Ijọba afidihẹ agbede meji Iwọ Orun sọ fun awọn oniwe irohin ni ebute ọkọ ofurufu ni Ikẹja wipe on ri wipe Ijọba ti ko ni si ẹgbẹ alatako ni o dara fun wa ni ilẹ Nigeria nitoripe bẹni awọn ara ilu Ghana nṣe nilu wọn.

Ẹ jọwọ ẹ ba wa ṣe alaye kikun fun Oloye Osadebay na wipe IJỌBA ALAPA kan ṣoṣo ko dara rara, irẹjẹ ni o nmu wa fun awọn ara ilu ti nwọn ba jẹ anikanjọpọn bi ọpọlọpọ awọn oṣelu wa ni Nigeria.

Ẹ ma gbagbe wipe ni ilu Ghana ko si mi isita kan ti o gbọdọ ni ile meji, ko si gbọdọ fi eru gba ilẹ, bi awọn oṣelu wa kan ṣe ngba ilẹ ni Ikoyi, ti nwọn nyọ ta wọn lowo gere ni Nigeria fun awọn ajoji. Tabi nwọn ṣebi a ko ri gbogbo nkan ti awọn oṣelu wa na nṣe ni?

Olotu, o di ọjọ idibo ni a o lo sọ fun wọn wipe awa kiṣe Ọbọ-Idere. Boya ki nwọn ba le ma ri aye ṣẹ wa jẹ ni nwọn ṣe nke'gbe wipe Ijọba ti ko si alatako ni awọn nfẹ. Ọlọrun ko ni fun wọn ṣe rara.

Emi ni,
Agọ Owu, Ọmọ Abati
Abẹokuta

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

## Minisita Eleke Eebu

Otutu-Ọyẹ ti a ma nri ninu oṣu kejila ninu ọdun (oṣu ti ẹ npe ni December) ni o ma jẹki a mọ wipe a fẹ pari ọdun kan ki a tun mu omiran, ṣugbọn a ko ri otutu-ọyẹ ni Eko ninu oṣu December ọdun yi rara a fi orişirişi eebu ti a ngbọ lẹnu awọn ọmọ ẹgbẹ oşelu Alakukọ wipe ẸNIKAN KO MỌ IWE TO ẸNIKAN ninu awọn minisita meji kan ti nşe gbọnmi si omi-ko-to.

Emi ko ba wọn wi, gbogbo wọn ni nwọn ti ri nkan jajẹ ninu awo. Eyi ti ko ni adiẹ lọgba, a ni tolotolo tabi ẹran ẹlẹdẹ ni agbala ti yio fi ṣe ọdun Keresimesi pẹlu awọn ọmọ ati iyawo rẹ. Kini emi Ayiluka ni lọgba lati fi ṣe ọdun? Ko si nkankan, afi ọpọlọpọ pali iwe Ẹ KU ỌDUN, Ẹ KU IYEDUN, ti awọn ọrẹ ati ẹmẹlẹbi fi nranṣẹ si mi lati ilu okere bi Ibadan, Abẹokuta, Kano, London, ati Sierra—Leone. Ẹ jọwọ ẹnyin ọkawe mi, ṣe pali-iwe ẹ ku ọdun yi ni ngo jẹ lowurọ ọjọ Ọdun Keresimesi? Ọrọ na ko ti ye mi si.


E Ka

Oro Olotu ti o kun Fun oro isiri ati oye loju ewe kerin.



E ma ka

Iwe Irohin ELETI-OFE

Ti o kun fun IROHIN ALADUN Losose.


## Tolotolo Odun

Boya ọrọ tolotolo ti mo ntẹ ẹnu mọ nigbagbogbo ni o jẹ ki ẹnikan ti orukọ rẹ njẹ Muyidin Durojaiye ninu awọn ọkawe mi fi iwe ọrọ apejuwe bi TOLOTOLO ỌDUN ṣe ma ndun ni akoko Keresimesi ranşẹ si mi.

Muyi Durojaiye ti o fi ọrọ apejuwe na ṣọwọ si mi ni ninu iwe kan ti awọn eleto ẹkọ Ijẹbu Ipinlẹ Iwọ Orun ntẹ jade, ti nwọn npe ni AWORẸRIN ni on ti ka a. Ẹ jọwọ ẹ jẹ a jọ gbadun ọrọ tolotolo ọdun Keresimesi na, on nivi:

Tolotolo ni ao pa fi ṣe ọdun Keresimesi yi. Adiẹ l'apal 'ọdun t'o kọja. Mo Mo gbọ wipe tolotolo dun ju adiẹ lọ, Nigbati mo ba jẹ ẹ ni ngo mọ.

Iyẹ tolotolo wa dudu, o si ndan, sugbọn ogbe ori rẹ ati jọjọ agbọn rẹ pupa. Iyẹ idi rẹ gun a si ma da bi abẹbẹ nigbati o ba ga a.

Lati ọjọ ti baba ti raa ni mo ti ntọju rẹ. Emẹta ni mo nfun u l'onjẹni ojumọ. Ọka baba ni o fẹran ju, O si tun ma nşa ewe njẹ.

## Baba Onitolotolo

Şe ẹnyin na wa ri wipe ọrọ tolotolo ko jẹbẹ lọdọ awọn akọwe? Bi o ba nwa ipo nibi iṣẹ ti o nfẹ ki ọga rẹ ki o sun ọ si iwaju, ki o di ọga kekere nibi iṣẹ rẹ, sa lọ ra tolotolo lọdọ awọn ara Ilọrin ni Idumọta ki o gbe lọ fun ọga rẹ loru, nisisiyi ni wa di ọga apapandodo

## Oku Baba-Nla

O dun mi pupọ ti nko le lọ si ibi oku Ọgbeni March ẹniti gbogbo awọn ara Eko nmọ awọn oni mọto tasi (taxi) mọ adapọ orukọ rẹ ni BABA-NLA ti o jalaisi ni ọsẹ ti o kọja yi. Mo gbọ wipe eni - nla ni o nşe nkan nla ni isinku BABA NLA nitoripe MOTO NLA pẹlu POSI NLA (Coffin) ni nwọn fi sinku rẹ, ILE -NLA ni awọn ebi BABA - NLA ra ni Ikoyi fun iboji rẹ.

Baba - Nla, o digba, o şe!

## Gbere Beyioku

Oloye Akin Fagbenro-Beyioku, mo gbadun rẹ fun ọrọ ọmọ ọkọ ti o sọ fun awọn sọbọsọla ti nwọn nfẹnu atẹ sọrọ abuku si awọn alkukọ ọmọ Yoruba ti nwọn fẹ şe ẹgbẹ ọmọ Yoruba, Ẹgbẹ ọmọ Ibo wa, Ẹgbẹ ọmọ Isobo wa, ẹgbẹ ọmọ Kalaba wa ninu Alakukọ, ẹnikan ko bu wọn, şugbọn omo ale Yoruba ni yio mọ fi ọwọ osi juwe ile baba rẹ.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


THE ANSWER TO TROPICAL CONDITIONS

★

UNMATCHED AFTER SALES SERVICE

★

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA, IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA, ONITSHA.

Sub - Distributors :—

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN-CITY . ONITSHA . ABA.

# British Professor to Help Recruit Staff For Our University

LONDON—Professor Norman Haycocks, Professor of Education and Deputy Vice-Chancellor of Britaion's Nottingham University, is having talks with Government departments and in his own University in the hope of recruiting more staff to serve in West Africa.

This follows a six weeks tour in Ghana and Nigeria where he was impressed with the atmosphere os zest and eagerness for education to expand at all levels and with the "very high level of ability of those holding responsible positions in education."

The abject of the tour, organised by the British Council, was to enable the Professor, as Chairman of his University's Committee for the Secondment of Staff to Universities in Developing Countries to familirise himself with the problems of West African universities, especially in staffing matters.

During his tour, Professor Haycocks visited all five universities in Nigeria and three in Ghana. He also visited technical institutes, teachers' trainin colleges of all grades, and secondry and primary schools.

In both countries he had noticed a tendency towards development in the sciences engineering and agricultural science, which was 'very wise' in view of the countries' own internal needs, and a concern by the universities to help solxe the shortages of graduate teachers, he said.

# Akoka Yoruba

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Bi Ifa ko ba fọ ire, awọn babalawo yio bere lọwọ Ifa ẹbọ wo ni ki nwọn ru, ki ibi ma ba ṣe ba ẹmọbinrin na bi o ba di aya ọmọkunrin na. Ohun yowu ti a sọ wipe ki ọmọbinrin na ki o ṣe, awọn obi ọmọkunrin na ni yio ru ẹbọ na.

Bi awọn obi ẹmọkunrin yi ti nd' nṣiti nwọn si ndi elube, ni nwọn yio ma jẹ ọwẹ lọdọdun ni oko baba ọmọbinrin na. Ni ọjọ ijẹ-ọwẹ yi, nwọn yio bẹ ọpọlọpọ enia lati lọ ṣiṣẹ ni oko ana wọn, awọn yio si se ounjẹ fun gbogbo awọn ẹniti o ba wọn lọ si oko ọwẹ na.

Ni afikun gbogbo eyi, bi ijẹ ana wọn ba jo, wọn ni lati pa koriko tabi esun tabi ọkẹ tabi ki nwọn ja agba tabi ki nwọn ge opo fun kikọ ile na. Ise yowu ti o ba kan ni ile ana, tayọtayọ ni awọn Yoruba ifi ṣe e nitori nwọn gba pe ẹniti o fun ni ni ọmọ pari ore. (koi ti pari)

## Olofintoto Ni:

## Se Egbon Njoku Fe Gba Ise Biney Ni?

( O bẹrẹ loju ewe kẹta )

on pẹlu iyawo rẹ jọ gba die ninu iṣe eti ebute na ọkẹ ti Biney ti nṣe lati bi ogoji ọdun sẹhin. Bi iṣe na ṣe tẹ awọn ọmọlẹbi Njoku lọwọ ko ye mi si.

### Ija Ko D'ola

Mo gbọ ti awọn Sọrọsọrọ kan ni ọrọ na dabi ẹni wipe aja ti nsan eegun ti a so mọ aja na lọrun nisisiyi o. Ọrọ eebu ko ran nkan ti a ia silẹ yi ju ki awọn alamojuto eto Ijọba ilẹ wa ṣe iwadi bawo ni ẹgbọn Raymond ti o njẹ Bernard tiṣe di oniṣẹ ebute ọkọ ni Apapa ati wipe kini o fa a ti a fi fẹ gba iṣẹ na lọwọ ọga awọn lebira ti nwọn ti nṣe iṣẹ na ri. Mo gbọ ti Ọgbẹni T O S Benson paapa nsọ fun awọn lọrẹ rẹ laipẹ iyi wipe irọ ni awọn ẹmọ Ibo kan ti nwọn npe ọkan ninu wọn ni Okafor inpe mọ on, ti nwọn ni on ni on nṣe eke ọrọ awọn ọṣelu ọmọ Ibo fun Ọlọla] Tafawa Balewa lẹhin. O ni oko si nkan ti o jọ bẹ rara.

AKIYE: Ẹ ra iwe irohin Eleti-Ofẹ ni ọsẹ iti mbọ ki ẹ gbọ orişirişi ọrọ aşiri bi nkan ti nlọ si ni Nigeria.

— OLOTU

# E Ku Ipalemo Odun Keresimesi




# Sora Re Loju Ona Moto

Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti bere ọsẹ Isọra loju ọna mọto ninu ọsẹ yi, nwọn si ti bẹrẹsi kọ awọn dẹreba awa mọto kakiri ilu Ibadan ati awọn ti nwọn nfi ẹsẹ rin loju titi bi awọn ṣe ni lati ma lo oju ọna—moto na si. Ọgbẹni Adeyi, minisita alamojuto eto oju ọna ni ko din ni trinwọ jamba moto ti o nṣe loju ọna moto ni oṣoṣu ni Ipinlẹ na, o si npa ọpọlẹpọ awọn enia lọkunrin ati lobinrin ni a pa fọn.

# Eleti-Ofe D'araba

## Annual Report of Broadcasting:

# B.B.C. Cover The World In News

LONDON—In 1955 there were 237 million radio sets in the world; today the figure is about 400 million, and in some of the developing countries the number has been doubling almost every year. This phenomenal growth in radio sets, the establishment of new broadcasting systems all over the world and the expansion of others both internally and externally, are among the points noted in the Annual Report of the BBC for 1962-63 in referring to increasing competition in the field of external broadcasting. But despite this stiffening competition, states the Report; the reputation of the BBC External Service (which broadcast in English and 40 other languages) remain as high as ever. Audience studies have confirmed in a number of areas the the extend of listening to the BBC, and a significant and encouraging feature emerging from these studies is that BBC programmes have a particular appeal for younger people.

Thus, half the listeners in the U.S.S.R. whose ages were established were under thirty (and information came from 75 towns), and two-thirds of those in France are under twenty 'There is reason to believe,' says the report, 'that a similar situation exists in many other parts o f the world. A recent survey of listening in Morocco showed that a higher proportion of people under the age of thirty that over the age of thirty listened to the BBC, and the same result has been found in other surveys."

Many listeners referred appreciatively to the reliable information provided by the BBC. For example two recent surveys outside Europe, one in South Vietnam and one in Egypt, have shown that the BBC is regarded by listeners as the *most* reliable source of world news, talking into account even local radios and newspapers.

Similar appreciation was found in Eastern Europe, and one example quoted, for a report which reached was found the BBC from the Eastern Zone of Germany, illustrates again that younger as well as older people value BBC broadcasts "I am a worker in Wittenberg, 22 years old," it ran, 'and I like to listen to you. There is no radio station which reports in such detail and so truthfully about world events as does London radio. Please accept sincere thanks, and carry on like that. We need you'.

**Read**
**And Advertise**
**In the**
**Eleti-Ofe**
**a Weekly News-paper**

# British Sixth Formers To Learn About Nigeria

LONDON — British sixth-formers from over one-hundred schools will learn about Nigeria during a a study conference on the Commonwealth next month arranged by the Royal Commonwealth Society in London

The two-day conference is called "The Commonwealth looks at itself" Outlining Nigeria's viewpoint will be Mallam Osman Ahmadu-Suka, First Secretary and Education Attahe in the High Commission of the Federal Republic of Nigeria in London.

After an address by Mallam Ahmadu-Suka, entitled Africa looks at the Commonwealth the sixth-formers along with a number of Nigerian students in London will break up discussion groups, with the address as their theme. Later there will be questions to the speaker.

The Commonwealth study conference, to be presided over by Sir Hilary Blood, a former Governor of the Gambia, will also include speakers from Canada, Australia, and India.

**We wish all our Readers Merry Christmas and Happy New Year.**



# Dokita Aluko ni Sile Meje to Fun Awon Osise

EKO—Oluko Ile iwe giga julọ ti Ile-Ifẹ (University of Ife), Dokita S A Alukọ ni ṣile meje ojumọ ko pọ ju fun Ijọba ile Nigeria ma san fun awọn oṣiṣẹ fun owo iṣẹ wọn. Ni ijẹta ni o sọrọ yi ni iwaju awọn Oluwadi Morgan, ti nwọn nṣe iwadi bi o ba yẹ ki nwọn fi owo kun owo-oṣu ti awọn oṣiṣẹ ngba nisisiyi.

Dokita Aluko ni o jẹ aṣiwaju fun awọn ọmọwe olukọni meji miran ti nwọn wa si iwaju awọn oluwadi na lati wa sọ ti wọn lori iwadi ọran owo oṣoṣu yi.

Ninu alaye ti Dokita Aluko ṣe si iwaju, o ni o yẹ ki awọn alamojuto Ijọba da ile igbẹjọ kan silẹ fun awọn oṣiṣẹ ati awọn ọga ti nwọn gba wọn ṣiṣẹ. O ni nibẹ ni nwọn yio ti ma gbọ ọrọ ti o ba ndun awọn oṣiṣẹ na lọkan nwọn yio si ma ribi ba wọn dasi fun wọn.

Dokita Aluko ni ko dara ki iru kotu awọn oṣiṣẹ bayi jẹ amugbalẹhin fun Ijọba, ti o ba jẹbẹ, ko ni lese nilẹ lati le ṣe ẹtọ fun awọn oniṣẹ mọ.

## Nwon Yole

Dokita Aluko ni ki a sọ gasikia, awọn oṣiṣẹ wa ya ọlẹ, nwọn si ni imẹlẹ, wọn ki fẹ iṣẹ ṣe. O ni gbogbo asiko ti nwọn ko ba fi ṣe iṣẹ aje fun anfani ilu ni nwọn nlo lori a-da-iṣẹ silẹ ati ki a mọ ṣe ikunsinu lori wipe Ijọba ko fun wọn lowo to.

Ọmọwe Aluko ni ogoji wakati tabi wakati merin lelogoji to lati fi ṣiṣẹ fun ọjọ meje ti mbẹ ninu ọsẹ kan ju wakati merinlelogun gbọn ti ewọn oṣṣọ ni yen lawọn nfẹ.

IMODU JẸ PANLA :

## Ni Gari Ni O Jeki Osise Yole

EKO—Pẹlu iyanu ni gbogbo awọn enia ti nwọn wa si Ọdan nibi iwadi ti adajọ Morgan nṣe, nwo Ọgbẹni Michael Imoudu, agbọrandun gbogbo awọn oṣiṣẹ ilẹ Nigeria, nigbati o bẹresi fi ẹja panla mu gari ti o ru wa si ile iwadi na lati fi iru onjẹ ti awọn oṣiṣẹ ma njẹ lojojumọ han awọn Oluwadi.

Ọgbẹni Imodu ni tani le jẹ iru onjẹ bayi ti o le ni okun ninu fi sisẹ, o ni ko si. Imodu ni nkan ti o fa a nfi panla mu gari, a nnu ọpọlọpọ gari mọ ẹwa, ti awọn lebira Eko ma npe ni ADALU, ni owu oṣu ti ko to nkan ti Ijọba ati awọn Oyinbo onişowo nsan fun awọn oṣiṣẹ na.

Bi Ọgbẹni Imodu ti fi panla mu gari na tan ni o ni inu nrun on, ọkunrin kan ti nwọn pe ni onişegun awọn oṣiṣẹ si jade, o ko awọn horo ẹyọ egbogi kan fun un wipe ki o mu ki o to bọ silẹ ninu apoti ti o ti nsọrọ.

## E Ku Odun Keresimesi

A ki ẹnyin ọkawe Eleti-Ọfẹ jake jado ilẹ Nigeria, ti ẹ duro ti wa lati ibẹrẹ ọdun yi wipe ẹ ku ipalẹmọ ọdun Keresimesi ati ọdun titun, Oluwa jẹki eyiti mbọ ṣoju ẹmi gbogbo wa.

— OLOTU

## Iya Alawo Toku L'Eko Jidide Ninu Saro, O Fowo Ran Enia Sile

tun merin ti o fi di awọn aṣọ ti yio lo lọwọ, o ni owo pepa ti on ri lọwọ iya alawo na ti o nku loju on to irinwo pọnun (£400). Ninu owo na ni o ti ko awọn kan fun on wipe ki ko awọn enia on l'Eko ki nwọn ri nkan lo fun ọdun Keresimesi.

Nigbati nwọn iwe ikede iku (Obituary) ti nwọn fi kede iku arabirin na, ti o nwọn lẹ mọ'ta, han baba Saro ti o wa jiṣẹ na, nṣe ni on na daku gbọin; nwọn lati gbee lọ si ọdọ dokita ki on na to mọ ibi ti on gbe wa.

Ayiluka Ni:

## Ibadan Ko Gba Gbere!

(O bẹrẹ loju ewe karun)

Ayiluka ni ọrọ akin ti Oloye Fagbenro-Beyioku sọ fun awọn sọọsọla inu ẹgbẹ ọmọ Alakukọ lori ẹgbẹ ọmọ Yoruba Parapọ ti nwọn fẹ da silẹ kakiri gbogbo ile Nigeria laipẹyi jẹki oniran esi ọrọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ Ibadan fi sọrọ ẹgbẹ ọmọ Yoruba na, awọn bi Ọgbẹni Akinjinde ni awọn "SỌBỌBOLESAN" faṣọ bo ẹnu wọn, nwọn ni nigbati awọn Ibo n ẹgbẹ ọmọ onilẹ ti wọn, awọn Yoruba ti o wa ninu ẹgbẹ oselu Alakukọ ko sọ wipe ki nwọn ṣe ẹgbẹ na rara.

Awọn ara Ibadan ni awọn ko gba gbẹrẹ rara, ki olukulu dọmu iya rẹ gbe o!

### Olofintoto Fomo Yo

Emi Ayiluka kiṣẹ OLOFINTOTO, sugbọn ki nto pari ọrọ mi ti ọsẹ yi mo fẹ ṣe ẹnuforo kan fun ẹnyin ọkawe mi nipa nkan ti ọrẹ mi, OLOFINTOTO Eleti-Ọfẹ fẹ sọ fun awọn ọmọ Igbomina mọ Offa, Ekiti mọ Odo Ogun. Ma tilẹ jẹki gbogbo rẹ dọsẹ ti mbọ ti ẹ o ma gbọ gbogbo rẹ lẹnu on na.

Ẹ ku ipalẹmọ ọdun!

## Awon Ara Owu Faake Kori Lori Oye Ti Ijoba Fe Gba Lowo Adegbenro

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Alaye ti a gbọ wipe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ṣe lori ọrọ na ni wipe awọn fura si i wipe ẹsẹ-gigun ni Oloye Adegbenro na lo ti oye na fi tẹ lọwọ nigbati o jẹ ni idurin nitoripe Alhaji Adegbenro paapa ni minisita alamojuto eto Ijọba Ibilẹ ni asike Ijọba awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ (AG).

Gbara ti awọn ara Owu ti gbọ ọrọ na ni gbogbo awọn Oloye wọn nile ati loko ti nṣe "kinla, awa ko yọ Balogun wa loye, kini kan Ijọba ninu ọrọ a nrọ ni loye? O dabi ẹni pe awọn alamojuto eto Ijọba wa nfẹ di ọrọ oṣelu mọ ọrọ Oye." Awọn ara OWU NI A KO GBAUN.

M o gbọ wipe ẹnikan ti nwọn npe ni I jani Ademola ni awon Ijọba ni ki Ọba Olowu gbe oye Balogun Owu na fun.

Gẹgẹbi eto ti o wa ninu ofin awọn oloye Ipinlẹ Iwọ Orun ẹnikẹni ti Ijọba ba fọwọ si oye rẹ nigbati awọn ara ilu rẹ ba ti yan an ni o ni eto lati wa ṣe aṣoju awọn enia re ninu ile igbimọ awọn lọbalọba ni Ibadan.

Oye meji pataki ni Alhaji Adegbenro jẹ ninu Ẹgba, o jẹ Balogun awọn ara Owu, oye ti o fẹ di ijangbọn yi ati Ẹkẹrin gbogbo awọn Ẹgba nile loko.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos
Phone 23370; Editor; (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O Box467